**OSE KEJE**

IBEERE EWONIDAHUN

**IPIN A: EDE : AKAYE**

**Ka awon ayoka isale wonyi ki o si dahun awon ibeere ti o tele e**

Ori yeye ni mogun,taise lo po. Idogbe omo Memuna ara Iloro sese ti ibi ise de ni irole ojo yii. O jokoo si ita lati reti Jokootade omo aburo baba re, ti o ran ni akara, eyi ti yoo fi jeko.

Jejeniwa ni aburo baba idogbe. Ati pinnisin ni o ti gba idogbe mora' ti o si fi si enu ikose mekaniiki nigba ti o pe omo odun metala. Idogbe ja fafa lenu ikose, kii pa ibi ise je, tegan ni heen. Omo to se e mu yagan ni. Ni ojo buruku esu gbomi mu yii, jijokoo ti Idogbe jokoo sita pelu aso ise re, ti o doti koja aala, ni o sokunfa kiko ti awon olopaa ko o mo awon elegiri ti o sese sose ni adugbo keji. Ki a to seju pe, Idogbe ti ba ara re ni atimole olopaa.

1. Ta ni o fi aijebi sun atimole? a. Jokootade b. Jejeniwa c. Idogbe d. Memuna
2. Itumo 'elegiri' ni a. olopaa b. ole c. mekaniiki d. alakara
3. Ta ni Idogbe ran nise? A. Memuna b. Jokootade c. Jejeniwa d. olopaa
4. Oro ti a le fi dipo 'pinnisin' ninu ayoka yii ni a. odo b. kekere c. agunbaniro d. agba
5. Ohun ti o je ayoka yii logun nip e a. opo elese ni o wa ni atimole olopaa b. ole nikan ni atimole olopaa wa fun c. elese kan ko ni lo laijiya d. enikeni ni o le di eni atimole olopaa

Ojo kan soso ojo a maa bori oda. Laipe, Ajewole gbagbe pe igba kan wa ri ti Toorera iyawo oun je agan ti o n fi owo osun nu ogiri gbigbe, ti o n room leyin adie, ti o bu puru sekun, ti awon n fi ojoojumo serahun omo. Nigba ti o ya, omo wa po loode re,oro re gbogbo si dayo. O ti kuro ninu o-lounje-nile-fi –tulaasi-gbawe. Ko maa ru hangogo mo. O kuro ninu a-n-mu-hanturu, a-n-ya-ojule aafaa ati adahunse kiri. Adun si wa gbeyin ewuro fun un.

6. Ta ni agan nigba kan ri? a. Toorera b. Adahunse c. Aafa d. Alagemo
7. “Igba oda” toka si igba a. aisan b. aijeun c. aisanra d. airomobi
8. Adun ti o gbeyin ewuro ni a. yiye gbaawe b. riri omo bi c. nini omi lara d. bibo ninu aisan
9. _______ ni won se aajo fun a. Ajewole b. Adahunse c. Olokunrun d. Alagemo
10. Ori-oro ti o je mo aroko asapejuwe ni a. Aafin oba ilu mi b. Owo ko niran c. Imototo d. Ayeye ojo-ibi mi ti o koja
11. “Eko ile” je ori-oro fun aroko a. asapejuwe b. asariyanjiyan c. asotan d. ajemo-isipaya
12. Aroko wo ni eeyan meji ti maa n soro ni sise-n-tele? a. asariyanjiyan b. onisorogbesi c. onileta d. ajemo-isipaya
13. ________ maa n je igbese keta ninu leta aigbagbefe a. adiresi akoleta b. ikini ibere c. akole leta d. oruko akoleta
14. Igbeseti o maa n tele ori-oro ninu leta aigbagbefe ni a. koko- oro b. deeti c. ikini d. adiresi eni ti a kowe si
15. Kin ni o gbodo jeyo ni opin leta a. deeti b. oruko akoleta c. koko-oro d. adiresi eni ti a kowe si
16. Konsonanti aranmu ni a. [w] b. [k] c. [n] d. [s]

17. Konsonanti afafasefetepe ni a. [b] b. [h] c. [w] d. [f]

18. [Ɔ] je faweli a. oke /ahanupe b. ebake/ ahanudiepe c. ebado / ayanudiepe d. odo / ayanupe

19. Mofiimu ipile ninu “onijo” ni a. nijo b. jo c. oni d. ijo

20. Ipin si mofiimu “oselu” ni a. o-se-ilu b. o-selu c. o-se-i-lu d. o-se-lu

21. Ipin si silebu ‘penkelemeesi ni a. pen-ke-le-me-e-si b. pe-n-ke-le-me-e-si c. pen-ke-le-mee-si d. pen-kele-me-e-si

22. Ewo lo ba ilana akoto ode oni mu fun ‘oni aanu’ a. alaaanu b. alaaanu c. alaaanu
d. alaaanu

23. Ewo ni aranmo waye ninu iseda re? a. ijuuba b. awitunwi c. etile d. omoota

24. Iparoje jeyo ninu a. alaafia b. akaa c. owoori d. gbagbo

25. Ipaje faweli waye ninu a. orun b. sare c. aseje d. yoo

26. “Olu ri Sina ni igboro”. ‘ni igboro’ je a. apola ise b. apola eyan c. apola atokun
d. apola oruko

27. Oro _____ ni o maa n toka si ibi ninu gbolohun a. ise b. asopo c. atokun d. aponle

28. Oro ayalo afetiya ni a. Esiteri b. Bibeli c. Baibu d. Peter

29. Ewo ni oro ayalo? a. alawiiye b. alatupa c. alubarika d. alasoyan

30. Ewo ni o je mo isamulo afomo? a. omooba b. aroko c. wolewole d. araale

31. Afomo aarin wa ninu a. pejapeja b. idile c. ilejile d. atidade

32. “Omo iya” di “Omooya” nipase a. ipaje faweli b. iyopo faweli c. aranmeyin d. aranmowaju

33. Apetunpe waye ninu a. wase b. lilo c. eewo d. darandaran

34. “Won tan ina sinu ile, o mo roro”. ‘roro’ je a. oro-ise b. oro-oruko c. oro-eyan d. oro-aponle

35. Oro-asopo ninu ‘A lo si oko’ ni a. lo b. A c. oko d. si

36. “Ade ati Ojo lo wa isu loko”. ‘ati’ je a. oro-ise b. oro-asopo c. oro-aponle d. oro-apejuwe

37. “Yala teju lowo tabi ko ni, oun ni maa fe”. Oro-asopo inu gbolohun yii ni a. Yala… Teju b. Teju… lowo c. tabi… ko d. Yala… tabi

38. Ewo ni a seda nipa sise apetunpe? a. atije b. omokunrin c. osoose d. aseju

39. Oro iseda ni a. ere b. ape c. ipe d. eba

40. Igbese ti o waye ninu ‘ je isu’ ti o di jesu ni a. aranmo b. ipaje c. ijeyopo d. iforo

41. “Sade ni o se obe wa” je apeere gbolohun a. akiyesi alatenumo b. abode c. alakanpo d. isodoruko asopato

42. Oku ejo loba I ds jemo asa a. isile b. isigun c. isupo d. iselu

43. A kii jokoo seti odo jemo eko a. ifarabale b. ibowofagba c. imototo d. imowon-ara-eni

44. Ewo ni ajokoose? A. Ekun meran b. Bojuboju c. Eye meloo d. Ayo

45. ------------ ni a maa n ki pe “E ku owo lomi” a. akoseyege b. onisile c. abiyamo d. omolokuu

## ITUMO EDE

Tumo gbolohun ti o wa ni ibeere 46- 50 si ede Yoruba

46. The man is very generous a. Okunrin naa gbajumo pupo b. Okunrin naa je alafe eeyan c. Okunrin naa lawo gan-an d. Okunrin naa kanra gan-an
47. The economy will be buoyant this year a. Oro-aje n fe si lodun yii b. Oro-aje yoo bureke si lodun yii c. Oro-aje yoo yipada lodun yii d. Oro-aje n fe atunse lodun yii
48. I believe him a. Mo gba o gbo. b. Mo le gba a gbo c. Mo gba a gbo d. Mo le gba o gbo
49. They have been singing. a. Won ti le korin b. Won ti le maa korin c. Won a ti korin
   d. Won ti n korin
50. The food is nutritious. A. Ounje naa ladun b. Ounje naa sara loore c. Ounje naa ta sansan
   d. Ounje naa fani mora